**IDAGBASOKE ONIGBAGBỌ**

**2 Peteru 1: 1-21**

**EKỌ 454 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Nitori bi ẹnyin ba nṣe nkan wọnyi, ẹnyin ki yio kọṣẹ lai" (2 Peteru 1:10).**

## Peteru Oniwaasu

Simoni Peteru tun n kọ iwe miiran. Ẹ jẹ ki a feti silẹ si iṣẹ́ ti o ti ọdọ Ọlọrun wá, o jẹ ti wa lonii pẹlu, bi o tilẹ jẹ pe a ti waasu rẹ̀ ni nnkan bi ẹgbẹwa ọdun sẹyin. Awọn iwe miiran maa n darugbo, a si n kọ awọn titun miiran: ṣugbọn ọrọ Ọlọrun ni amọna tootọ nigba gbogbo fun igbesi-ayé wa ojoojumọ, bi a ba si tẹle awọn imọran rẹ̀, a o ri Jesu ni ọjọ kan.

## Awọn Ileri ti kò le Yẹ̀

A ri ninu Bibeli, ọpọlọpọ "awọn ileri rẹ̀ ti o tobi pupọ ti o si ṣe iyebiye". Eyi ti iwọ ti gbọ́ lọpọlọpọ igba ni "Ẹnyin ọmọ, ẹ mã gbọ ti awọn obi nyin ninu Oluwa:….. ki o le dara fun ọ, ati ki iwọ ki o le wà pẹ li aiye" (Efesu 6:1, 3) eyi ni ofin kin-in-ni pẹlu ileri fun ọjọ́ gigun ati alaafia. Awọn ileri miiran ni: "Ninu ile Baba mi ọ̀pọlọpọ ibugbe li o wà:… Emi o tún pada wá, emi o si si mu nyin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà, ki ẹnyin le wà nibẹ pẹlu" (Johannu 14: 2, 3). Ileri miiran, ti a ri ninu ori iwe ti o kẹyin ninu Bibeli ni: "Ibukún ni fun awọn ti nfọ̀ aṣọ wọn, ki nwọn ki o le ni anfani lati wá si ibi igi iye na, ati ki nwọn ki o le gba awọn ẹnubode wọ inu ilu na" (Ifihan 22:14). Ẹni kan ti ka ileri ẹgbẹrin le ni ẹgbaarin o le mẹwaa ninu Bibeli (8,810).

## Awọn Onigbagbọ ti n so Eso

A kọ́ ninu ẹkọ wa ti o kọja pe a ni lati ka Bibeli ki a ba le "dagba" nipa ti ẹmi. Ninu ẹkọ wa ti oni, a ri awọn ohun ti a gbọdọ fi kun iriri Onigbagbọ wa, a sọ fun wa pe bi a ba ṣe eyi a o jẹ́ iranwọ ẹlomiran, a o si di Onigbagbọ ti n so eso. A ranti ohun ti Jesu sọ fun igi ọpọtọ nì ti ko so eso. O wá lati ọdun dé ọdun, o n wá eso, ṣugbọn ko ri nnkankan. Nigba ti o di ọdun kẹta, O wi pe, "Ke e lulẹ". Ninu awọn eso ti a n ri ni igbesi-ayé Onigbagbọ́ ni: "Ifẹ, ayọ̀, alafia, ipamọra, iwa pẹlẹ, iṣore, igbagbọ́, iwa tutù, ati ikora-ẹni-nijanu"(Galatia 5:22, 23).

## "Ọmọ-ọwọ" ninu Kristi

Awọn ti a ṣẹṣẹ gbala jẹ "ọmọ-ọwọ" ninu Kristi, ṣugbọn wọn le dagba bi a ba fi ounjẹ ẹmi bọ wọn daradara. Ninu 1 Peteru 2:2, a ka pe, "Bi ọmọ-ọwọ titun, ki ẹ mã fẹ wàra ti Ẹmi na eyiti kò li ẹ̀tan, ki ẹnyin ki o le mã ti ipasẹ rẹ̀ dàgba si igbala". "Wàra ti kò li ẹtàn" jẹ́ ojulowo eyi ti ko ni abula. A mọ̀ wara bi ounjẹ ti o pe: o kún fun aọn nnkan ti o n mú ara dagba ti o si n mú ara lagbara. Bi ẹni kan ba fi ẹfun ati omi sinu igo ọmọ-ọwọ́, ki o si fẹ fi rọ ọ, ọmọ naa ko ni mu un, bi o ba si mu un o le ṣaisan. Ko ni si ohun ti o n mu ara dagba ninu rẹ̀ eyi ti o wà ninu wara, bi o tilẹ jẹ pe o le jọ wara. Kò si ohun ti a le fi dipo Ọrọ Ọlọrun, a si ni lati ka a, ki a ba le dagba nipa ti ẹmi.

Peteru fun wa ni iṣiro lati ṣe: "ẹ fi iwarere kún igbagbọ́; ati imọ kún iwarere; ati airekọja kún imọ; ati sũru kún airekọja; ati iwa-bi-Ọlọrun kún sũru; ati ifẹ ọmọnikeji kún iwa-bi-Ọlọrun; ati ifẹni kún ifẹ ọmọnikeji". Ki ni idahun, tabi aropọ rẹ̀? Idahun rẹ̀ ni pe: "Bi ẹnyin bá ni nkan wọnyi ti nwọn bá si pọ̀, nwọn ki yio jẹ ki ẹ ṣe ọ̀lẹ tabi alaileso ninu imọ Oluwa wa Jesu Kristi". A sọ fun wa pe bi a ba n fi gbogbo nnkan wọnyii kun iriri Onigbagbọ́ wa, a ki yoo fasẹyin.

Ni ọna keji, a n fi idahun fun ọrọ kan naa, bi a ko ba fi wọn kún igbesi-aye wa. "Ẹniti o ba ṣe alaini nkan wọnyi, o fọju, kò le riran li okere, o si ti gbagbe pe a ti wẹ̀ on nù kuro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀ atijọ".

Idahun wo ni o ba igbesi-aye rẹ mu? Njẹ o wà ninu ẹgbẹ́ awọn "ti nso eso" tabi ẹgbẹ́ awọn ti oju wọn kò ri kọja ayika wọn tabi ti wọn fọju? A sọ fun wa pe bi a ba ṣe alai ni nnkan wọnyii, a fọju, a ko si le riran lokeere rére, tabi pe a ti gbagbe pe a ti gbà wá là lẹẹkan ri.

Peteru mọ pe lai pẹ oun yoo lọ si ile rẹ̀ ọrun, o si sọ pe oun mọ̀ pe o ṣe danindanin lati "rú nyin soke". O mọ pe lai pẹ, oun ni lati fi ẹmi oun lelẹ fun Oluwa oun.

**Lori Oke Mimọ́**

Iriri iyanu ti Peteru mẹnukan ninu ori iwe yii ni akoko ti Jesu mú Peteru, Jakọbu ati Johannu pẹlu Rẹ̀ lọ si Ori Oke Ipalarada. Oju Jesu ràn bi oorun, aṣọ Rẹ̀ si funfun bi imọlẹ. Inu Peteru dùn lati wà nibẹ, o si sọ bayii pe, "Oluwa, o dara fun wa lati mã gbé ihin: bi iwọ ba fẹ, awa o pa agọ́ mẹta sihin; ọkan fun ọ, ati ọkan fun Mose, ati ọkan fun Elijah" (Matteu 17:4). Lojiji awọsanma didan ṣiji bò wọ́n, ohùn kan si fọ si wọn, "Eyiyi li ayanfẹ Ọmọ mi, ẹniti inu mi dun si gidigidi; ẹ mã gbọ́ tirẹ̀". Ẹru ba Peteru, Jakọbu ati Johannu, wọn si da oju wọn bolẹ. Nigba naa ni iran yii nù mọ́ wọn loju, wọn si ri Jesu nikan ti o duro.

**Imọlẹ ninu Okunkun**

Ko si ọ̀kan ninu wa ti o ti iri iriri bi iru eyi, ati pe ni akoko yii lẹẹkọọkan ni awọn eniyan n ri iran. Ṣugbọn lọjọ oni a le mọ ohun ti o yẹ lati ṣe dajudaju bi ẹni pe Jesu n bá wa sọrọ lojukoju, ti a si n gbọ́ ohun Rẹ̀ ketekete. Peteru wi pe: "Awa si ni ọ̀rọ asọtẹlẹ ti o fẹsẹ-mulẹ jubẽlọ; eyiti o yẹ ki ẹ kiyesi bi fitila ti ntàn ni ibi òkunkun". Njẹ o mọ ohun ti ọrọ ti o daju yii jẹ? On ni Bibeli Mimọ́. Bi ẹni kan ba sọ fun ọ pe oun ti gbọ́ ohùn Ọlọrun ti o bá oun sọrọ, boya iwọ le ṣe iyemeji rẹ̀, kò ni si ẹni ti eyi yoo ṣe ni anfaani ni tootọ bi ko ṣe ẹni ti o gbọ́ Ohùn naa. Nigba miiran Ọlọrun maa n bá eniyan sọrọ ni ohùn ti a le gbọ́; ṣugbọn a ni Ọrọ Ọlọrun, a ni lati ka a, ki a si kọ́ ifẹ Ọlọrun.

Awọn ajihinrere ti lọ si gbogbo ayé, wọn si ti sọ nipa Jesu fun awọn eniyan, awọn oloootọ alufaa n waasu Ọrọ yii ninu Ile Isin ati lori ẹrọ gbohungbohun; a si n fi iwe itankalẹ Ihnrere ranṣẹ si gbogbo ayé. Ijọ Igbagbọ́ Apọsteli n fi Iwe Itankalẹ Ihinrere ranṣẹ si ilu okeere ati erekuṣu ti o ju (200) igba lọ, a si ti tumọ iwe Itankalẹ Ihinrere yii si ede ti o ju (70) aadọrin lọ.

A le ra Bibeli tabi Majẹmu Titun ni owo kekere ni ilẹ wa. O yẹ ki a fiyesi i gidigidi, nitori ki i ṣe ọrọ eniyan bi ko ṣe Ọrọ Ọlọrun. "Nitori asọtẹlẹ kan kò ti ipa ifẹ enia wá ri; ṣugbọn awọn enia mimọ́ Ọlọrun nsọrọ lati ọdọ Ọlọrun bi a ti ndari wọn lati ọwọ́ Ẹmi Mimọ́ wá".

Lọjọ oni, a ti tẹ apa kan Bibeli ni ọta-le-ni-ẹẹdẹgbẹfa o le marun-un (1,165) ède. Ni Ilu Amẹrika nikan, a ta ẹẹdẹgbẹta ọkẹ (10,000,000) Bibeli ni ọdun 1959. Japan ni o tẹle e ni Bibeli tita, nibi ti a ta ọkẹ mẹta-le-laadọrun ati ẹẹdẹẹgbẹrinla din mọkan-lelaadọrun (1,886,909) ni ọdun kan naa. Ẹgbẹ oni-Bibeli ti Japan sọ pe lẹyin ogun Ajakaye keji, o din diẹ ni egbeje ọkẹ (27,074,553) Bibeli ni wọn ti tà, ati pe laaarin ọdun 1876 si 1944, ẹgbaasan (18,000) Bibeli pere ni a tà.

Ọdọmọkunrin ati ọdọmọbirin, ẹ ti gbọ́ ọrọ pataki lati ẹnu Peteru, ọ̀kan ninu "awọn enia mimọ́ Ọlọrun" ti o sọrọ gẹgẹ bi "Ẹmi ti dari" rẹ̀. O daju pe iwọ yoo ṣe rere bi o bá "fiyesi" ọ̀rọ naa.

**AWỌN IBEERE**

1. Sọ diẹ ninu awọn ileri nla nla ti a le ri ninu Bibeli.
2. Sọ nnkan marun-un ti a sọ fun wa pe ki a fi kún igbagbọ wa.
3. Ki ni a sọ nipa awọn ti wọn kuna nnkan wọnyii?
4. Bawo ni Peteru ṣe mọ pe lai pẹ oun yoo kú, oun yoo si lọ lati wà pẹlu Jesu?
5. Ki ni ṣẹlẹ lori Oke Ipalarada?
6. Ta ni kọ Bibeli?
7. Darukọ Ẹni mẹta ti o wà ninu Iwa Ọlọrun eyi ti Peteru mẹnukan ninu ori iwe yii.
8. Ọna wo ni Ọlọrun n gba ba wa sọrọ lonii?